ÈDÈ YORÙBÁ · YORUBA

# Irinṣẹ́ Àgbègbè Ìpínlẹ̀ New York

Ìtọ́sọ́nà ohun èlò fún àwọn aṣíkiri Ará New York

Oṣù Kẹsán/Kẹwàá Ọdún 2025





**New York Immigration Coalition**
nyic.org

Àgbáríjọ Àjọ Ìwọlé-jáde New York ṣe àgbékalẹ̀ irinṣẹ́ yìí láti pèsè ohun èlò fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ wa àti àwọn alájọṣepọ̀ wa tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú wọn. Irinṣẹ́ yìí máa ń wà ní ìmúdójúìwọn nígbàgbogbo dá lórí ìyípadà àwọn òfin àti ìlànà.

Imudojuiwọn to kẹhin: 10.28.2025

**Atọ́ka àkóónú**


- Ìlera 3
- Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde 5
- Àwọn Àtìlẹ́yìn ní Àtìmọ́lé 8
- Àwọn ohun àmúlò ìdílé 9
- Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́ 10
- Ìrólágbára owó 11
- Ìjọba tiwa-n-tiwa 12
- Mọ Àwọn ẹ̀tọ́ Rẹ 13
- Ààbò Àgbègbè 14
- Àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ NYS 15

# Ìlera




### Ìṣèdúró ìlera

- Àwọn ènìyàn ìpínlẹ̀ New York lè gba ìdójútòfò ìlera ti ìlú àti ti oko-òwò nípasẹ̀ Àjọ Elétò Ìlera Ìpínlẹ̀ NY.
  - Tí o bá pegedé fún ètò ìdójútòfò ìlera Medicaid, Àkànṣe Ètò Ìdójútòfò Ìlera (Essential Plan), tàbí Ìdójútòfò Ìlera Ọmọdé (Child Health Plus), ìforúkọsílẹ̀ ṣí sílẹ̀ láì ní gbèdéke.
  - Àkókò ìforúkọsílẹ̀ fún ètò ìbánigbófò ìlera àfiṣòwò ti parí báyìí
    - Fèrèsé ìforúkọsílẹ̀ to ṣí sílẹ̀ ní ó bẹ̀rẹ̀ láti 1 Oṣù kọkànlá si 15 Oṣù kíní.
- Bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀
  - Gba ìrànlọ́wọ́ ìforúkọsílẹ̀ ọ̀fẹ́ láti ọ̀dọ̀ Atọ́nà, fúnra rẹ̀ tàbí lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀. Wá Atọ́nà ní info.nystateofhealth.ny.gov/ipanavigatorsitelocations.
  - Pe Ibùdó Aṣojú Oníbàrà Ipò Ìlera NY ní 1-855-355-5777 (TTY: 1-800-662-1220).
  - Lórí ayélujára ní nystateofhealth.ny.gov. Ẹ̀yà Ìtàkurọ̀sọ kan wà lórí wẹ́búsáìtì lákókò àwọn wákàtí ibùdó aṣojú oníbàrà láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ fún pípari ìbẹ̀wẹ̀ rẹ.
  - Àwọn olùgbé Ìlú New York: pe 311, tẹ àtẹ̀jíṣẹ́ "CoveredNYC" sí 877-877, tàbí ṣàbẹ̀wò sí on.nyc.gov/healthinsurance fún ìrànlọ́wọ́ àti àfikún àwọn ohun èlò.
- Wá àlàyé ọlọ́pọ̀ èdè nípa ètò ìlera ní info.nystateofhealth.ny.gov/InformationalMaterials

### Òfin One Big Beautiful Bill (OBBBA)

- Ìjọba Àpapọ̀ láìpẹ́ jọjọ gbé Òfin One Big Beautiful Bill (OBBBA) wọlé.
- Òfin OBBBA lè ní ipa lórí Medicaid àti Ètò Pàtàkì, ṣùgbọ́n kò sí àwọn àyípadà lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Lọ́wọ́lọ́wọ́, ìlẹ́tọ̀ọ́sí àti àwọn ànfàní jẹ́ bákannáà.
- Láti rí àlàyé àtìgbàdégbà, ṣàbẹ̀wò sí info.nystateofhealth.ny.gov/stay-connected

### Àwọn àyípadà nínú Agbègbè Ìlera fun Àwọn Olùgbà DACA

- Bẹ̀rẹ̀ láti 31 Oṣu Kejọ, 2025, àwọn olùgbà DACA kòní ní ẹ̀tọ́ sí àwọn ètò ìṣèdúró ilera ti Òfin Ìtọ́jú Alábọ́dé (ACA).
- Kò sí àyípadà fún níní ẹ̀tọ́ sí àwọn ètò mìíràn, bíi Ètò Ìlera Pàtàkì tàbí Àwọn ètò Ìlera tí ó péye.
- Fún àlàyé síwájú sí lórí àgbègbè ìlera fún àwọn olùgbà DACA, ṣàbẹ̀wò sí nilc.org/resources/affordable-care-act-for-daca-recipients-a-guide-to-apply
- Àwọn àyípadà àfikún lè wà fún àgbègbè ìlera àwọn olùgbà DACA láìpẹ́. Láti wà ní ìmúdójúìwọ̀n lórí àwọn àyípadà, yẹ healthcare.gov wò.

- **Àwọn Ètò Ìlera tí Medicaid Gbé Ìnáwó Rẹ̀ fún àwọn Olùṣíwọ̀lú tí Orúkọ Wọn Kò Sí Nínú Ìwé Ìlú Ìpínlẹ̀ New York**
- Àwọn olùṣíwọ̀lú tí wọn kò sí nínú ìwé ìlú tí wọ́n ń gbé ní ìpínlẹ̀ New York tí wọ́n jẹ́ ẹni ọdún 65 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, tí wọ́n sì kúnjú ìwọ̀n àwọn ohun tí wọ́n ń béèrè láti ní ẹ̀tọ́ sí owó pàtó, ni wọ́n yẹ fún ìrànlọ́wọ́ ìlera Medicaid (ní àtakò sí Medicaid pàjáwìrì nìkan)
- Àwọn ọmọdé tí kò ni ìwé-àṣẹ lábẹ́ ọdún 19 ni ó ní ètò sí Child Health Plus (CHP), èyítí ó pèsè ètò ìṣèdúró ìlera ọ̀fẹ́ tàbí olówó pọ́ọ́kú láìbìkítà owó tó ń wọlé tàbí ipò ìṣíwá.
- Medicaid kì í ṣe 'idiyele gbogbo gbòò ' àti pé kò ní ipa lórí ìlẹ́tọ̀ọ́sí káàdì ọmọ-ìlú.
- Bí o ṣe lè forúkọsílẹ̀
  - Tí o bá ní Medicaid pàjáwìrì lọ́wọ́lọ́wọ́, o lè yípadà sí Medicaid kíkún nípa títẹ̀lé àwọn ìtọ́ni nínú lẹ́tà láti Ipò Ìlera NY.
    - O tún lè yan láti tẹ̀síwájú nípa gbígba Medicaid pàjáwìrì nìkan.
  - Tí ìwọ kò bá ní ìṣèdúró, tí o kò sì ní Ìtọ́jú Pàjáwìrì tẹ́lẹ̀, o gbọ́dọ̀ ṣe ìbẹ̀wẹ̀ rẹ nípasẹ̀ Ẹ̀ka Iṣẹ́ Àwùjọ Agbègbè rẹ, tàbí Ìṣàkóso Àwọn ohun Èlò Ọmọnìyàn ìlú New York City.
  - Tí ìwọ bá nílò ìrànlọ́wọ́ tàbí ní àwọn ìbéèrè, pe Ipò Ìlera NY ní 1-855-355-5777. Ìrànlọ́wọ́ èdè wà.

### Àyẹ̀wò Àrùn Jẹjẹrẹ

- Àwọn àyẹ̀wò àrùn jẹjẹrẹ lóòrèkóòrè máa ṣe ìrànlọ́wọ́ àwárí àrùn jẹjẹrẹ ní ìbẹ̀rẹ̀ nígbà tí ó rọrùn jù láti wòsàn.
- Púpọ̀ nínú àwọn ètò ìbánigbófò ìlera ló máa ń gbé ìnáwó àwọn àyẹ̀wò àrùn jẹjẹrẹ.
- Tí ọ kò bá ní ètò ìbánigbófò, NYS máa ń pèsè àwọn àyẹ̀wò ọ̀fẹ́ fún àrùn jẹjẹrẹ ọmú, ojú-ara, ìfun ńlá.
- Fún àlàyé síwájú sí i, ṣàbẹ̀wò sí health.ny.gov/diseases/cancer/services

# Ìlera



**Àwọn Abẹ́rẹ́ Àjẹsára Aláìléwu tí ó sì Múnádóko ti wà fún COVID-19, Ibà, àti RSV**

- Àwọn àjẹsára jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn irinṣẹ́ tí ó lágbára jùlọ láti dáàbò bo ìlera àti dènà àwọn àìsàn tó le. Wọ́n ti dán wọn wò dáradára, bójú tó wọn, ati pé àwọn ògbóntàrìgì oníṣègùn ti wọn ṣeé gbẹ́kẹ̀lé tí dábàá wọn.
- Gbáralé àwọn orísun ti ó ṣeé gbẹ́kẹ̀lé bíi CDC, Ẹ̀ka Ìlera tí Ìpínlẹ̀ New York, tàbí olùpèsè ìlera rẹ láti ṣe ìpinnu tí ó dára jùlọ fún ìwọ àti ẹbí rẹ.
- Abẹ́rẹ́ Àjẹsára àrùn COVID-19 ti ọdún 2025-2026 tí a mú d'ójú ìwọ̀n ti wà nílẹ̀.
  - Ìmúdójúìwọ̀n abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID yìí ti bo ọ̀pọ̀lọpọ̀ onírúurú kòkòrò afàìsàn tó ń jà lọ́wọ́lọ́wọ́ tí a ń rí ní Ilẹ̀ New York àti ní U.S.
  - FDA dábá pé àwọn àgbàlagbà tí ó jẹ́ ọdún 65 àti jù bẹ́ẹ̀ àti àwọn ẹni-kọ̀ọ̀kan tí ó wà ní ọdún 12-64 pẹ̀lú ó kéré jù àìsàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ papọ̀ lẹ́ẹ̀kan (ipò ìlera tó le) gba afáralókun.
  - Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 ti ọdún 2024-2025, kàn sí cdc.gov/covid/vaccines
  - Láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára COVID-19 tí a mú d'ójú ìwọ̀n ní ibùdó tó wà ní ìtòsí rẹ, kàn sí vaccines.gov
  - Tí a bá ní àwọn àpẹẹrẹ àrùn COVID-19 tàbí tí o bá wà nínú ewu àti kó àrùn náà, lọ ṣe àyẹ̀wò.
    - Àyẹ̀wò àrùn COVID-19 lè jẹ́ kí o ṣe ìpinnu lórí ohun tí o máa ṣe tí o bá ń ṣe àìsàn, bíi gbígba ìtọ́jú àsìkò láti dènà àìsàn tó lágbára tàbí ìyaraẹnisọ́tọ̀ lójúnà àti mú àdínkù bá ewu títan àìsàn kálẹ̀.
- Àjẹsára àrùn ọ̀finkìn 2025-2026 yóò wà lárọ̀ọ́wọ́tó ní ìgbà òtútù 2025.
  - Abẹ́rẹ́ àjẹsára fún ibà tí wọ́n ti ṣe àtúnṣe rẹ̀ máa ń dáàbòbo ẹni lọ́wọ́ onírúurú ibà mẹ́ta.
  - Ètò CDC dábàá àjẹsára ibà fún gbogbo ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn bẹ̀rẹ̀ láti oṣù 6 àti dàgbà jù bẹ́ẹ̀ lọ.
  - Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 65 àti dàgbà jù bẹ́ẹ̀ lọ, àwọn ènìyàn tó ní pàtó ipò àìlera ọlọ́jọ́ pípẹ́, àwọn ọmọdé àti arọ̀bọ́, àti àwọn aboyún ni wọ́n wà nínú ewu gíga jù láti ní ìlọ́lù líle láti ibi ìkọlù ibà.
- Abẹ́rẹ́ àjẹsára fún Fáírọ́ọ̀sì Afàìsàn sí Ẹ̀dọ̀fóró àti Òpó-mímí ti wà lárọ̀ọ́wọ́tó.
  - Abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí lè ṣe ìrànwọ́ ìdènà sí àìlera òpó-mímí ìsàlẹ̀ tí RSV ṣokùnfà.
  - A dábàá abẹ́rẹ́ àjẹsára yìí fún olúkúlùkù ní ìbámu sí ojú-ọjọ́ wọn àti àwọn ewu ohun okùnfà mìíràn.
    - Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 75 àti àwọn tó dàgbà jù bẹ́ẹ̀ lọ wà nínú àwọn tí a dábàá kí wọ́n gba àjẹsára.
    - Àwọn ènìyàn tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 60 sí 70 leè bá àwọn olùpèsè ìtọ́jú ìlera wọn sọ̀rọ̀ bóyá wọ́n wà nínú ewu gíga ìkọlù àìsàn RSV líle.
    - Àwọn olóyún leè dáàbòbo àwọn ọmọ wọn lọ́wọ́ ìkọlù RSV nípasẹ̀ gbígba àjẹsára alábiyamọ. Àwọn aboyún lè kànsí dókítà ìtọ́jú aboyún/onímọ̀ nípa obìnrin fún àlàyé díẹ̀ si.
  - Àwọn oògùn tún wà fún àwọn ọmọ ìkókó àti àwọn ọmọdé kékeré láti dènà RSV tí a pè ní nirsevamab àti clesrovimab.

**Ìbẹ́sílẹ̀ Àrùn Olóde àti Abẹ́rẹ́ Àjẹsára**

- Àìmọye ìbẹ́sílẹ̀ àrùn olóde ló ti wáyé láìpẹ́ yìí, ó jẹ́ àrùn àkóràn tó léwu fún àwọn ọmọdé kékèké.
- Àjẹsára àrùn olóde, ṣegede, àti àrùn ìta (MMR) múnádóko gan-an láti dènà àrùn olóde.
  - Abẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ni wọ́n máa ń fún ní àwọn ìgbà 2. Àkọ́kọ́ máa ń jẹ́ ìfúnni ní ọmọ oṣù 12-15 àti èèkejì ní ọmọ ọdún 4-6.
  - Àwọn ọmọdé, ọ̀dọ́, àti àwọn àgbàlagbà tí wọ́n kò gba àjẹsárá lè gba ìwọ̀n abẹ́rẹ́ àjẹsára 2 láti dí èyí tí wọ́n kò gbà tẹ́lẹ̀ fún ọ̀sẹ̀ 4 sira wọn
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí cdc.gov/measles

**Abẹ́rẹ́ Àjẹsára HPV**

- HPV jẹ́ fáírọ́ọ̀sì kan tó lè tàn kálẹ̀ nípasẹ̀ ìfarakanra tí ó sì lè ṣokùnfà àwọn àrùn jẹjẹrẹ bíi àrùn jẹjẹrẹ ojú-ara àti ọ̀nà ọ̀fun.
- Wọ́n dámọ̀ràn àjẹsárá HPV fún gbogbo ènìyàn tí kò tíì pé ọmọ ọdún 26.
  - Àwọn ọmọdé tí ọjọ́-orí wọn jẹ́ 11–12 yẹ kí wọ́n gbàá ní ìgbà 2, fífún ní oṣù 6 sí 12 síra wọn.
  - Àwọn èèyàn ọmọ ọdún 15 sí 26 yẹ kí wọ́n gbàá ní ìgbà 3, ní oṣù 6 síra wọn.
- Àwọn èèyàn tó ti lé ní ọdún 27 yẹ kí wọ́n kànsí olùpèsè ìtọ́jú ìlera wọn.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò cdc.gov/hpv/vaccines

# Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde



**Àwọn owó Ìṣíwá sísan Tuntun**

- Léhìn tí a ti sanwó owó-orí Ìjọba Àpapọ̀ àti ìnáwó HR. 1 sọ ọ́ d'òfin, awọn owó-sísan fun Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìfilọ́lẹ̀ ìṣíwá ti yípadà tàbí pọ̀ si.
- Àwọn ìgbówólórí wọ̀nyí ti múlẹ̀ láti 22 Oṣù Keje, 2025 àti 21 Oṣu Kejọ, 2025.
- Àwọn ìmúlò fún àwọn ìyọkúrò owó-sísan tún ti ní ìdádúró nínú àwọn ìlànà ìfisílẹ̀.
- Díẹ̀ nínú àwọn àyípadà tí ó lé ní ipa lórí àwọn olùbẹ̀wẹ̀ ni:
    - Ìbẹ̀wẹ̀ Ààbò
        - Owó-sísan titẹ́lẹ̀: $0
        - Owó-sísan tuntun: $100
        - Owó àtúnṣe tuntun $100 ọdọọdún kan fún 'ààbò tún wà fún sísan'
        - Kò sí àwọn ìyọkúrò tí a gbà láàyè fun owó - sísan yìí.
    - Àwọn ìwé àṣẹ Iṣẹ́ tí ó ní í ṣe Pẹ̀lú ibi ààbò (EAD) / Awọn ìwé àṣẹ iṣẹ
        - Owó-sísan titẹ́lẹ̀: $0
        - Owó-sísan Tuntun: $550 (fún olùbẹ̀wẹ̀ ìgbà akọkọ)
        - Owó-sísan tuntun: $275 owó ìsọdọ̀tun
    - Ipò Ìdáàbòbò Onígbàdíẹ̀ (TPS)
        - Owó-sísan titẹ́lẹ̀: $50
        - Owó-sísan tuntun: $550
    - Ọmọdé Aṣíkiri Pàtàkì (SIJ)
        - Owó-sísan titẹ́lẹ̀: $0
        - Owó-sísan tuntun: $250
    - Àṣẹ Ìgbélù Fúngbà Díẹ̀
        - Owó ti Tẹ́lẹ̀: Onírúurú
        - Owó Àfikún Tuntun: $1,000
        - Owó àfikún tuntun yìí jẹ́ fún àwọn ènìyàn tí wọ́n ti fún ní àṣẹ ìgbélù fúngbà díẹ̀ tí wọ́n sì wà ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà.
        - Owó àfikún náà yóò jẹ́ gbígbà nìkan bóyá/nígbà tí wọ́n bá ti fọwọ́sí ìwé àṣẹ rẹ láti gbé ìlú fúngbà díẹ̀. Má ṣe sanwó nígbà tí o bá fi fọọmù I-131 ránṣẹ́.
- Fún àtòkọ kíkún ti àwọn owó-sísan ìṣíwá tuntun àti àwọn àfiwé sí àwọn owó-sísan ìṣáájú, jọ̀wọ́ ṣàbẹ̀wò sí immigrantjustice.org/research/explainer-trump-and-congresss-punishing-new-immigration-fees


**Ìfòfindè Ìrìn-àjò**

- Ní 9 oṣù kẹfà, Ìṣèjọba Trump ṣe àmúṣẹ ìfòfindè tó ń dènà ìrìn-àjò wọ orílẹ̀-èdè U.S. fún àwọn ènìyàn láti àwọn orílẹ̀-èdè 19.
- Ìfòfindè ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ wà lórí àwọn orílẹ̀-èdè Afghanistan, Burma, Chad, Republic of Congo, Equatorial Guinea, Eritrea, Haiti, Iran, Libya, Somalia, Sudan, àti Yemen.
- Ìfòfindè díẹ̀ wà lórí àwọn orílẹ̀-èdè Burundi, Cuba, Laos, Sierra Leone, Togo, Turkmenistan, àti Venezuela.
- Ìfòfindè ọ̀hún ní ipa lórí gbogbo ènìyàn tó wà ní ìta orílẹ̀-èdè U.S tó wá láti àwọn orílẹ̀-èdè wọ̀nyí àti pé ó mú àdínkù bá wíwọlé wọn sí orílẹ̀-èdè U.S., tí ó sì tún ń mú àdínkù bá bí ó ṣe ṣeé ṣe sí láti sọ ìwé ìwọ̀lú wọn dọ̀tun tàbí láti fi ọjọ́ kún un.
    - Ìfòfindè díẹ̀ ọ̀hún ń dènà jíjẹ àǹfààní àwọn ìwé ìwọ̀lú oko-òwò, ìgbafẹ́, àti ti mọ̀lẹ́bí.
    - Ìfòfindè kíkún ń dènà jíjẹ àǹfààní àwọn ìwé ìwọ̀lú oko-òwò, ìgbafẹ́, àti ti mọ̀lẹ́bí tó fi mọ́ àwọn ìwé ìwọ̀lú tó lè yọrí sí ìgbélùú fún ìgbà pípẹ́, tí a tún mọ̀ sí "àwọn ìwé ìwọ̀lú aṣíwọ̀lú."
- Ìfòfindè náà kò kan àwọn tí wọ́n ní ìwé ìgbélùú lọ́wọ́lọ́wọ́, àwọn ìwé ìwọ̀lú ẹbí kan, tàbí àwọn ènìyàn orílẹ̀-èdè Afghanistan tí wọ́n ní ìwé ìwọ̀lú Aṣíwọ̀lú Pàtàkì.
- Tí o bá wá láti ọ̀kan nínú àwọn orílẹ̀-èdè wọ̀nyí tí o sì ní àwọn ìfiyèsí lórí ìwé ìwọ̀lú rẹ, bá agbẹjọ́rò sọ̀rọ̀.

**Ìgbaniláàyè ìwọ̀lú onígbà díẹ̀ ti CBP One àti Ìgbaniláàyè fún àwọn ènìyàn orílẹ̀-èdè Cuba, Haiti, Nicaragua, àti Venezuela (CHNV)**

- Ìjọba fi ìfitónilétí ránṣẹ́ pé òhun ń gbèrò láti fa'gi lé ipò ìgbaniláàyè ìwọ̀lú onígbà díẹ̀ ti àwọn ènìyàn tí wọ́n wọ orílẹ̀-èdè U.S.:
    - Nípasẹ̀ ìpàdé CBP One; àti
    - Lábẹ́ ètò ìgbaniláàyè ìwọ̀lú onígbà díẹ̀ ti Cuba, Haiti, Nicaragua, àti Venezuela (CHNV)
- DHS ti fi ìfitónilétí ránṣẹ́ sí àwọn tí wọ́n gba àyè ìwọ̀lú onígbà díẹ̀ nípasẹ̀ ímeèlì, méèlì, tàbí nípasẹ̀ áàpù.
- Tí o bá wá sí orílẹ̀-èdè U.S. nípasẹ̀ lílo CBP One tàbí CHNV, tí o kò sì tíì fi orúkọ sílẹ̀ fún àǹfààní ìṣíwọ̀lú mìíràn:
    - Ọjọ́ ti lọ lórí ipò ìwọ̀lú onígbà díẹ̀ rẹ àti ìgbaniláàyè iṣẹ́.
    - Wọ́n lè nawọ́ gán ọ kí wọ́n sì lé ọ padà sí orílẹ̀-èdè rẹ.
- Tí o bá ti fi orúkọ sílẹ̀ sí USCIS fún àǹfààní ìṣíwọ̀lú mìíràn, bíi ìsádi, o lè ríbi tẹ̀síwájú láti máa wá àǹfààǹì náà tí o sì lè pegedé fún ìgbaniláàyè iṣẹ́ nípasẹ̀ àǹfààní ọ̀hún.
- Tí o bá gba ìfitónilétí pé wọ́n ti fa'gi lé ipò ìgbaniláàyè ìwọ̀lú onígbà díẹ̀ rẹ, bá agbẹjọ́rò lọ́rọ̀ ìṣíwọ̀lú kan sọ̀rọ̀ ní kíákíá láti mọ àwọn àṣàyàn tó wà nílẹ̀ fún ọ.

# Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde



**Ìgbésẹ̀ ìdádúró fún àwọn èwe tí wọ́n dé (DACA / Deferred Action for Childhood Arrivals)**

- Nísìsiyìí, wọ́n ń pinnu nípa DACA lọ́wọ́ ní àwọn ilé-ẹjọ́. Ìyẹn túmọ̀ sí pé ọjọ́ iwájú ètò náà ò dájú.
  - Fún àlàyé díẹ̀ sí, ṣàbẹ̀wò sí homeishere.us/daca-guidance
- Lọ́jọ́ 12 Oṣù Kẹta, Ọdún 2025, ìpinnu ilé-ẹjọ́ tó ṣẹ̀ṣẹ̀ wáyé yóò gba àwọn tó forúkọsílẹ̀ fún DACA nígbà àkọ́kọ́ láàyè. Síbẹ̀síbẹ̀, kò tíì sí ìmúdójúìwọn ìtọ́nisọ́nà láti ọwọ́ USCIS.
  - Tí ọ bá yẹ ní yíyàn fún DACA tí ọ sì ń gbèrò láti fiwé béèrè fún ìgbà àkọ́kọ́, ó yẹ kí ọ bá agbẹjọ́rọ̀ ìṣíwọ̀lú tó ṣe é gbaralé sọ̀rọ̀ ṣáájú ìfiwé béèrè.
- Ẹjọ́ ń lọ lọ́wọ́, nítorí náà ó ṣe é ṣe kí àwọn àyípadà mìíràn wà sínú ètò náà.
- Ní báyìí, DHS yóò tẹ̀síwájú láti gba àti ṣe ìlànà ìsọdọ̀tun àwọn ìbéèrè DACA (pẹ̀lú ìbéèrè fún ìwé-àṣẹ iṣẹ́ àti ìlọsíwájú ìdásílẹ̀). DHS yóò gbà ṣùgbọ́n kò ní ṣe ìlànà àwọn ìbéèrè DACA àkọ́kọ́.
  - Tí o bá ní DACA lọ́wọ́lọ́wọ́, ipò rẹ ṣì tọ̀nà.
  - Tí DACA rẹ bá parí láàrín oṣù mẹ́fà tó ń bọ̀, tún un ṣe báyìí!
  - Tí o bá fi ìbẹ̀wẹ̀ DACA àkọ́kọ́ sílẹ̀ fún USCIS tí kò sì tí ì wà ní ìtẹ́wọ́gbà, ìbẹ̀wẹ̀ yẹn yóò wà ní ìdádúró. Kì yíò jẹ́ ṣíṣàáyan títí di ìgbà tí wọ́n bá sọ pé ó yá.
- Àwọn ẹnì-kọ̀ọ̀kan tí ó ti gba Ìgbésẹ̀ ìdádúró fún àwọn èwe tí wọ́n dé (DACA) lè báyìí fi Fọ́ọ̀mù I-821D (ìbẹ̀wẹ̀ ìsọdọ̀tun DACA) ati I-765 (ìbẹ̀wẹ̀ ìsọdọ̀tun ìwé-àṣẹ iṣẹ́) lórí ayélujára.
  - Ìforúkọsílẹ̀ orí ẹ̀rọ ayélujára wà fún àwọn tí wọ́n ní DACA lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí tí DACA wọn ti parí láàrín ọdún kan séyìn.
  - Fún àlàyé síwájú síi nípa DACA àti bí o ṣe lè ṣe ìsọdọ̀tun ipò DACA rẹ, ṣàbẹ̀wò sí uscis.gov/DACA.

**Ipò Ààbò Ònígbàdíẹ̀ (TPS / Temporary Protected Status)**

- Ìjọba orílẹ̀-èdè Améríkà lè yan orílẹ̀-èdè àjèjì fún TPS tí àwọn ipò kan, gẹ́gẹ́ bíi ìjà ọmọ ogun tàbí àjálù àdánidá, bá dènà àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè yẹn láti padà láìléwu.
- Ní àkókò tí a yàn, àwọn ènìyàn tí wọ́n ń béèrè fún tí wọ́n sì fún wọn ní TPS:
  - Wà ní ìdáàbòbò lọ́wọ́ ìlékúrò nílù.
  - Lè gba ìwé-àṣẹ iṣẹ́ ati nọ́mbà ààbò àwùjọ
  - Lè gba àṣẹ ìrìn-àjò
  - DHS kò lè fi wọ́n sí àtìmọ́lé nítorí ipò ìṣíwá wọn
- TPS jẹ́ ànfàní ònígbàdíẹ̀ tí kò yọrí sí ipò títílái. Síbẹ̀síbẹ̀, àwọn tí wọ́n ní TPS lè béèrè fún ànfàní àwọn aṣíkiri míràn tàbí àwọn ipò àjèjì tí wọ́n ní ẹ̀tọ́ fún.
- Àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n yàn lọ́wọ́lọ́wọ́ fún TPS:
  - Burma (Myanmar), El Salvador, Ethiopia, Haiti, Lebanon, Somalia, Sudan, South Sudan, Ukraine, Yemen
- Fún àlàyé orílẹ̀-èdè kan pàtó, àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́, àwọn àkókò ìforúkọsílẹ̀, àti àwọn ìmúdójúìwọn tuntun, ṣàyẹ̀wò uscis.gov/TPS.
- Gbogbo àwọn olùbẹ̀wẹ̀ TPS lè bayi lè báyìí fi Fọ́ọ̀mù I-821, Ìbẹ̀wẹ̀ fún Ipò Ààbò ònígbàdíẹ̀, lori ayélujára ní uscis.gov/i-821.
- Wọ́n ti ń ṣe àtúnyẹwò ìpínfúnni ti DHS tí ìjọba Biden ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀. Àtúnyẹwò DHS' sí àwọn ìpínfúnni ti TPS lè yọrí sí fífagi lé òfin ìpínfúnni TPS.
  - Ní 1 oṣù kejì, ọdún 2025, DHS fi òfin díẹ̀ de TPS fún àwọn ènìyàn orílẹ̀-èdè Venezuela.
    - Ètò TPS 2021 tí ó wà fún àwọn Aráàlú Venezuela ni wọ́n ṣètò láti fòpin sí ní 7 Oṣù Kọkànlá, Ọdún 2025.
  - Ní 20 Oṣù Kẹjọ, DHS gba àṣẹ láti fòpin sí TPS fún Honduras àti Nicaragua, èyí ti ìmúnádóko bẹ̀rẹ̀ ní 8 Oṣù kẹsàn
  - Ní 22 Oṣù Kẹsán, Ọdún 2025, DHS fòpin sí TPS fún Orílẹ̀-èdè Syria, bẹ̀rẹ̀ láti 21 Oṣù Kọkànlá, Ọdún 2025
- Àwọn aráàlú le tẹ̀síwájú láti máa ṣàyẹ̀wò àwọn ìpín TPS fún orílẹ̀-èdè wọn àti àkíyèsí ipò wọn.
- Tí ipò TPS rẹ bá ń parí lọ tàbí ó ti parí, bá agbẹjọ́rọ̀ lọ́rọ̀ ìṣíwọ̀lú kan sọ̀rọ̀ láti mọ àwọn àṣàyàn tó wà nílẹ̀ fún ọ kí o sì wo bóyá o pegedé fún àwọn ètò mìíràn.

# Àwọn ìmúdójúìwọn ìlànà ìwọlé-jáde

**Ìmúgbòòrò sí Ìyọkúrò ní Kíákíá Kúrò ní Ilẹ̀ Òkèèrè**

- Lọ́jọ́ 21 Oṣù Kinní, Ọdún 2025, Ẹ̀ka Àkóso Ààbò Ìlú ṣe ìmúgbòòrò èlò ìlànà kan tí a ń pè ní "ìyọkúrò kíákíá."
- Tẹ́lẹ̀, àwọn èèyàn tó wà láàárín máílì 100 sí ibodè nìkan ni ICE àti CBP máa ń lo òfin ìyọkúrò kíákíá fún àti láàárín ọjọ́ 14 tí wọ́n bá dé.
- Nísìsiyìí, àwọn ìjọba ti kéde pé àwon máa lo òfin ìyọkúrò kíákíá lórí ẹnikẹ́ni tí kò bá ní ìwé-àṣẹ nínú ìlú tí kò sì leè fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé wọ́n ti wà ní U.S láìkúrò fún ó kéré jù ọdún méjì ṣáájú ìgbà tí òfin mú wọn.
- Ìyọkúrò kíákíá gba ìjọba láàyè láti tètè lé èèyàn tí wọ́n gbàgbọ́ pé kò ní ìwé-àṣẹ kúrò nílùú, láì farahàn ní wájú olùdájọ́ ìṣíwọ̀lú.
- Lọ́wọ́lọ́wọ́, àwọn ìyàsọ́tọ̀ péréte ló wà fún ìgbésẹ̀ ìléni-kúrò-nílùú oní kíákíá.
    - Ìyàsọ́tọ̀ kan tó wà fún ìgbésẹ̀ ìléni-kúrò-nílùú oní kíákíá ni tí ẹnìkan bá ní ẹ̀rù ń ba òhun láti padà sí orílẹ̀-èdè rẹ̀ tó sì yegeníbi ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nuwò àyẹ̀wò ìbẹ̀rù. Èyí lè gbà wọ́n láyè láti fi orúkọ sílẹ̀ fún ìsádi.
- Ó yẹ kí ẹni kọ̀ọ̀kan mọ àwọn ẹ̀tọ́ wọn kí wọ́n sì tẹ̀lé ìgbésẹ̀ láti dáàbòbo ara wọn àti àwọn mọ̀lẹ́bí wọn, l'éyì tó pẹ̀lú gbígbé kiri ìwé àkọsílẹ̀ láti fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ ti gbé ìlú ju ọdún méjì lo tí ó bá ṣeéṣe.
- Fún àlàyé díẹ̀ sí, ṣàbẹ̀wò sí nilc.org/resources/know-your-rights-expedited-removal-expansion/



**ICE ní àwọn Ilé-ẹjọ́ Ìṣíwọ̀lú**

- Àwọn ICE ń nawọ́ gán àwọn aṣíwọ̀lú tí wọ́n ń fara hàn fún ìgbẹ́jọ́ ilé-ẹjọ́ tó ń gbọ́ ẹjọ́ ìṣíwọ̀lú.
- Ní ilé-ẹjọ́, agbẹjọ́rò ìjọba lè gbìyànjú láti da ẹjọ́ rẹ nù. Tí kò bá tíì pé ọdún 2 tí o dé sí orílẹ̀-èdè U.S., tí wọ́n sì da ẹjọ́ rẹ nù, o lè wà nínú ewu kí ICE nawọ́ gán ọ kí wọ́n sì fi ọ́ ránṣẹ́ padà sí orílẹ̀-èdè rẹ ní kíákíá. Ìléni-kúrò-nílùú oní kíákíá ni wọ́n ń pe ìgbésẹ̀ yìí.
- Bí o ṣe lè dáàbò bo ara rẹ
    - Tí o bá ríbi ṣe bẹ́ẹ̀, kópa níbi ìgbẹ́jọ́ ilé-ẹjọ́ ìṣíwọ̀lú láti òkèèrè.
    - Tí o bá pegedé, rí i dájú pé o ti fi ìbéèrè fún ìsádi tàbí àwọn ìbéèrè mìíràn sọwọ́ sí ilé-ẹjọ́.
    - Tí wọ́n bá nawó gán ọ, tí ẹ̀rù sì ń bà ọ́ láti padà sí orílẹ̀-èdè rẹ àti/tàbí orílẹ̀-èdè mìíràn, sọ àsọyé èyí fún ICE àti èyíkéyìí àwọn òṣìṣẹ́ ìṣíwọ̀lú.
    - Tí o bá ní ìbéèrè fún ìsádi ní ilé-ẹjọ́ nígbà tí wọ́n da ẹjọ́ rẹ nù, kò ní dáàbò bò ọ́. O gbọdọ̀ tún àlàyé ìbẹ̀rù ìfúngunmọ́ni tàbí ìfiyàjẹni rẹ ṣe.
- Mọ àwọn Ẹ̀tọ́ rẹ ní ilé-ẹjọ́:
    - O ní ẹ̀tọ́ láti tako kí wọ́n da ẹjọ́ rẹ nù kí adájọ́ tó dá ẹjọ́.
    - O lè béèrè fún kí agbẹjọ́rò ICE kọ ìbéèrè wọn láti da ẹjọ́ náà nù, kí o lè baà ráyè ṣàlàyé fún adájọ́ ìdí tí o ṣe fẹ́ tẹ̀síwájú pẹ̀lú ẹjọ́ rẹ àti láti béèrè fún ìrànlọ́wọ́ ajẹmọ́ òfin.
    - Tí adájọ́ bá da ẹjọ́ rẹ nù, o ní ẹ̀tọ́ láti pe ẹjọ́ kò-tẹ́mi-lọ́rùn. O lè tako ìpinnu yìí ní iwájú Ìgbìmọ̀ tó ń gbọ́ Ẹjọ́ Kò-tẹ́mi-lọ́rùn lọ́rọ̀ Ìṣíwọ̀lú (BIA). Rí i dájú pé o sọ fún adájọ́ ìṣíwọ̀lú pé o fẹ́ pe ẹjọ́ kò-tẹ́mi-lọ́rùn.
    - Tí o bá ń bẹ̀rù ìfúngunmọ́ni tàbí ìfiyàjẹni tí wọ́n bá dá ọ padà sí orílẹ̀-èdè rẹ àti/tàbí orílẹ̀-èdè mìíràn, sọ èyí fún adájọ́ níbi ìgbẹ́jọ́.

# Àwọn Àtìlẹ́yìn ní Àtìmọ́lé

**Bí ọ ṣe lè gbáradì fún ìwọ àti mọ̀lẹ́bí rẹ**

- Tí ọ bá ti ń ṣe ọmọ ìlú U.S. tí ọ sì ní ọmọ, ọ gbọdọ̀ ṣètò sílẹ̀ tí ó bá wáyé pé ICE, CBP tàbí àwọn aṣojú ìjọba mìíràn bá fi ọ́ sí àtìmọ́lé.
- Láti gbáradì, ọ gbọdọ̀:
  - Tọ́jú àwọn ìwé àdéhùn pàtàkì sí ààyè tí kò léwu tí àwọn ará ẹbí rẹ mọ̀ nípa rẹ̀.
  - Pinnu lórí ẹni tí ìwọ yóò nífẹ̀ẹ́sí láti tọ́jú àwọn ọmọ rẹ ti ọ kò bá láǹfààní láti mójútó wọn.
  - Yan ẹnìkan lábẹ́ òfin láti jẹ́ alábòójútó àwọn ọmọ rẹ.
    - Méjì nínú àwọn ọ̀nà tó wọ́pọ̀ láti yan alábòójútó lábẹ́ òfin ni;
      - Yíyan Ẹnìkan tó ní Ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Òbí
      - Alágbàtọ́ to wà Lárọ̀ọ́wọ́tó
  - Fọwọ́sí àwọn àfikún fọ́ọ̀mù fún ọmọ rẹ, tó pẹ̀lú Fọ́ọ̀mù Ìwé-àṣẹ Ìrìn-àjò tàbí Fọ́ọ̀mù Olùkànsí Fún Pàjáwìrì ní Ilé-ìwé.
  - Ọ sì tún lè fẹ́ ronú nípa fífọwọ́sí fọ́ọ̀mù Fí Fa Ase lé Aṣojú Ẹni Lọ́wọ́.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí vlpcny.org/get-help/immigration/planning-for-immigrant-parents

**Bí a ṣe lè ṣe ìkànsílé tí wọ́n bá fi ẹni sí àtìmọ́lé**

- Tí àwọn òṣìṣẹ́ ìṣíwọ̀lú tàbí agbófinró mìíràn bá fi ọ́ sí àtìmọ́lé, ọ ní àwọn ẹ̀tọ́ kan pàtó, tó pẹ̀lú ẹ̀tọ́ láti ní ìbáraẹnisọ̀rọ̀.
- Ọ ní ẹ̀tọ́ láti gba ìpè orí fóònù, bíi ìpè sí àwọn ẹbí, agbẹjọ́rọ̀, tàbí aṣojú ìjọba ìlú rẹ.
- Ọ lè pe ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ ìrànlọ́wọ́ ẹlẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ ti ọgbà àhámọ́ alákòóso ìṣíwọ̀lú láti kànsí olùrànlọ́wọ́ àti alátìlẹyìn.
  - Láti pe Ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ Ìrànlọ́wọ́ Ẹlẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ ti Àhámọ́ Ìṣíwọ̀lú ti Orílẹ̀-èdè, pe 9233# lórí fóònù ọgbà náà. Ọ̀fẹ́ ni ìpè lórí ago yìí, wọn kìí ṣọ́ ìpè sí fóònù yìí, àti pé ó wà fún ọ láti Ọjọ́ Ajé-Ẹtì, agogo 11 òwúrọ̀ sí 11 alẹ́.
  - Láti pe ago Ẹ̀ka Ajàfún Ẹ̀tọ́ Àwọn Mọ̀lẹ́bí Olùṣíwọ̀lú, l'éyì tó wà fún ọ ní Ọgbà Àhámọ́ Ìjọba Àpapọ̀ Buffalo, pe 716-427-4917, Ọjọ́ Ajé-Ọjọ́bọ̀, agogo 2-4 ọ̀sán àti 6-8 alẹ́.

**Bí a ṣe lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ẹni tó wà ní àtìmọ́lé**

- ICE lè fi àwọn tí kìí ṣe ọmọ ìlú sí ọgbà àhámọ́ tí ICE ń darí, ọgbà ẹ̀wọ̀n agbègbè, àti àwọn ọgbà àhámọ́ aládàáni.
- Ètò àhámọ́ alákòóso ìṣíwọ̀lú le ṣòro láti lò, èyí lè mú u ṣòro láti rí àwọn èèyàn rẹ tàbí bá wọn sọ̀rọ̀.
- Láti ṣàwarí ẹni tó wà ní àhámọ́ ICE lọ́wọ́lọ́wọ́:
  - Lọ sí locator.ice.gov kí ọ sì tẹ:
    - Orúkọ, orílẹ̀-èdè ìbí, àti ọjọ́-ìbí ẹni náà tàbí
    - Dígítì-9 A-nómbà
  - Olùṣàwarí ICE máa tọ́kasí ọgbà ìhámọ́ tí ẹni náà wà, ṣùgbọ́n ó lè gba àkókò díẹ̀ kí wọ́n tó farahàn lórí ètò yìí.
  - Tí ọ bá lérò pé èèyàn kan wà ní àtìmọ́lé ní ọgbà àhámọ́ ICE kan pàtó, ọ tún lè ní àǹfààní láti ṣàwarí wọn nípasẹ̀:
    - Wíwá wọn lórí accesscorrections.com. Tí orúkọ wọn bá hàn, Ó ṣeéṣe pé wọ́n wà ní àtìmọ́lé nínú ọgbà tí ọ tẹ orúkọ wọn sí.
    - Ọ lè kàn sí ọgbà náà tààrà ní ice.gov/detention-facilities
  - Tí ọ kò bá rí ẹni náà nípa lílo àwọn ètò orí ayélujára yìí, ọ lè kànsí ọ́fìsì agbègbè Aláṣẹ ICE àti Iṣẹ́ Imúkúrò (ERO): ice.gov/contact/field-offices
  - Fún àlàyé síwájú sí lórí wíwá ẹnìkan tí a ti mú tàbí tí ó wà ní ìhámọ́ aṣíkiri, ṣàbẹ̀wò sí nilc.org/resources/how-to-find-a-loved-one-after-a-u-s-immigration-arrest/
    - Àwọn ohun èlò yìí wà ní àwọn èdè 9 pẹ̀lú Gẹ̀ẹ́sì, Arabic, Kannada, Haitian Creole, Korean, Tagalog, Vietnamese, àti Spanish.
- Láti mọ ọjọ́ àti ibi ìgbẹ́jọ́ ẹnìkan:
  - Ṣàbẹ̀wò sí acis.eoir.justice.gov àti kí ọ sì tẹ dígítì-9 A-nómbà ẹni náà, tàbí
  - Pe 1-800-898-7180 kí ọ sì tẹ̀lé àwọn ìtọ́nisọ́nà wọn.
- Láti ṣàwarí ìrànlọ́wọ́ òfin:
  - Láti ṣàwarí àwọn àjọ tí kìí ṣe àfiṣòwò tó máa ń pèsè àwọn iṣẹ́ tó jẹmọ́ ọ̀ràn òfin lórí ọ̀rọ̀ ìṣíwọ̀lú ní ìdíyelé díẹ̀ tàbí lọ́fẹ̀ẹ́, ṣàbẹ̀wò sí immigrationadvocates.org/legaldirectory
  - Pe Ètò Àkànṣe Ìgbèjà Olùṣíwọ̀lú sórí 212-725-6422
- Láti gba ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ìsanwó béèlì:
  - Tí wọ́n bá bu owó béèlì tí èèyàn rẹ ò ní agbára láti san fun-un, wọ́n lè yẹ ní yíyan fún ìrànlọ́wọ́ owó béèlì ètò owó àkànlò fún béèlì
  - Fún àlàyé síwájú síi lórí owó béèlì ní ìpínlẹ̀ New York, ṣàbẹ̀wò sí envisionfreedom.org/get-support
  - Fún àtòjọ ètò ìrànlọ́wọ́ owó béèlì jákèjádò orílẹ̀-èdè, ṣàbẹ̀wò sí bit.ly/localbailfunds

# Àwọn ohun àmúlò ìdílé

**Ìrànlọ́wọ́ ìtọ́jú ọmọdé Promise NYC**

- Ní Oṣù kíní ọdún 2023, Ìlú New York ṣe ìfilọ́lẹ̀ Promise NYC, ètò tuntun tí yóò pèsè àwọn ìrànlọ́wọ́ ìtọ́jú ọmọdé fún àwọn ìdílé tí owó-àpawọlé rẹ kéré pẹ̀lú àwọn ọmọdé tí kò ní ìwé-àṣẹ tabi tí kì í ṣe ọmọ'lú, tí kò yẹ tẹ́lẹ̀ nítorí ipò ìṣíwá wọn.
- Wọ́n ti tún ètò náà ṣe àti pé yóò ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọdé tó lé ní 1,000 láti Oṣù keje Ọdún 2025 sí Oṣù kẹ́fà Ọdún 2026.
- Àwọn ìdílé lè ní ẹ̀tọ́ tí wọ́n bá:
  - Kò bá yẹ fún àwọn ọ̀nà ìrànlọ́wọ́ ìtọ́jú ọmọdé mìíràn.
  - Ní ọmọ kan ọjọ́-orí 0-13
  - Ní owó-àpawọlé ìdílé tí ó kéré sí 300% ìpele òṣì ìjọba àpapọ̀.
- Wọ́n gba àwọn mọ̀lẹ́bí níyànjú láti béèrè ní kíákíá pẹ̀lú àwọn àjọ agbègbè tí wọ́n yàn ní ìṣàkóso agbègbè wọn.
  - Bronx and Manhattan: Northern Manhattan Improvement Corporation (212-822-8300, nmic.org/promisenyc)
  - Brooklyn: Center for Family Life (718-438-9500, centerforfamilylife.org)
  - Staten Island: La Colmena (718-442-7700, lacolmenanyc.org)
  - Queens: Chinese-American Planning Council (718-358-8899, cpc-nyc.org)
- Jọ̀wọ́ ṣe àkíyèsí pé àwọn ààyè Promise NYC kò tó nkan, a sì gba àwọn ẹbí níyànjú láti fi ara wọn kún àtòjọ ìdúró tí àwọn ààyè tuntun bá ṣí sílẹ̀.



**Ètò ìrànlọ́wọ́ Itọju Ọmọde**

- Àwọn Ìdílé ti ní ẹ̀tọ́ báyìí fún ìrànlọ́wọ́ ìtọ́jú ọmọdé tí wọ́n bá ṣe 85% owó tí ìpínlẹ̀ ń wọlé tàbí kéré sí i.
  - Ìdílé kan yóò ní ẹ̀tọ́ tí wọ́n bá ní owó-àpawọlé ọdọọdún tí kò ju:
    - $73,869.56 fún ẹbí ẹléni 2
    - $91,250.63 fún ẹbí ẹléni 3
    - $108, 631.70 fún ẹbí ẹléni 4
    - $126,012.77  fún ẹbí ẹléni 5
    - $143,393.84  fún ẹbí ẹléni 6
  - Iye owó yóò dín kù sí 1% ti àpapọ̀ owó-àpawọlé ìdílé lókè téńté ààlà òṣì fún àwọn ẹbí tó kópa.
  - Iye ìgbàláàyè sísá jẹ́ 80
- Fún àlàyé síwájú síi àti láti rí i bóyá o lè ní ànfàní láti gba ìtọ́jú ọmọdé ní owó tó kéré tàbí lọ́fẹ̀ ko, ṣàbẹ̀wò sí ocfs.ny.gov/ccap.

**Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ Inú Oyún Ìpínlẹ̀ New York tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀**

- Bẹ̀rẹ̀ láti Ọjọ́ 1, Oṣù Kínní, Ọdún 2025, Ìpínlẹ̀ New York máa ṣe àmúwọlé Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ Inú Oyún tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀.
- Gbogbo òṣìṣẹ́ ilé-iṣẹ́ aládàáni New York tí ó bá ní oyún yóò lè gba àfikún wákàtí 20 tí a ó sanwó iṣẹ́ rẹ̀, fún Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí àìlera tàbí fún ìtọ́jú inú oyún.
- Ìtọ́jú inú oyún jẹ́ àfikún sí ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí àìlera tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀, kò sì nílò kí a máa jàn án pọ̀. O ti wà nílẹ̀, gbàrà tí òṣìṣẹ́ tí a gbà síṣẹ́ bá ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́.
  - Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ Inú Oyún tí a Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀ yàtọ̀ sí Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí Àìlera Ìpínlẹ̀ New York tàbí àwọn àgbékalẹ̀ tàbí ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ mìíràn.
  - Agbanişíṣẹ́ ò lè mú àwọn òṣìṣẹ́ ní dandan láti lo oríṣìí àwọn ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ wọn tán ná kí wọ́n tó lo Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí fún Ìtọ́jú Ìnú Oyún tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀.
- Àwọn òṣìṣẹ́ lè lo ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ yìí fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ oyún láàrin ọdún kan ṣùgbọ́n kò lè ju wákàtí 20 lọ láàrin ọ̀sẹ̀ 52.
- Gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ àwọn ẹka aládàáni ni lo Ìgbààyè-kúrò-lẹ́nu-iṣẹ́ torí fún Ìtọ́jú Ìnú Oyún tí a ó Sanwó Iṣẹ́ Rẹ̀ wà fún, láìwo ti iṣẹ́ wọn, ilé-iṣẹ́, tàbí aláàbọ̀ àkókò tàbí aláìsílórí-ipò àfikún àkókò.
- Ìtọ́jú inú oyún ni ìtọ́jú ìṣabiamọ bíi ìṣabiamọ ìkẹ́yinjádedàpọ̀mátọ̀ àti ìtọ́jú ìparí oyún.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí ny.gov/prenatal

# Àwọn ilé-ìwé àti ẹ̀kọ́



**Public School System (3K-12)**

- Ìpínlẹ̀ New York ṣe ìdánilójú fún gbogbo ọmọdé, láìka ipò àwọn aṣíkiri sí, ẹ̀tọ́ sí ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ àti ojúlówó, tí ó bẹ̀rẹ̀ ní ilé-ìwé ògoweẹ̀rẹ àti títí tí wọ́n yóò fi gba ìwé-ẹ̀rí ilé-ẹ̀kọ́ gíga dípúlómà, tàbí kí wọ́n dàgbà ní òpin ọdún nínú èyí tí akẹ́kọ̀ọ́ náà yóò di ọmọ ọdún 21.
- Àwọn ìdílé ní ìdánilójú ẹ̀tọ́ sí ìtumọ̀ àti ìtumọ̀-ọ̀rọ̀ ti gbogbo àwọn ìwé-àṣẹ tí ó ní àlàyé pàtàkì nípa ẹ̀kọ́ ọmọdé ní ọ̀nà tí ó bá àkókò mu.
- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè béèrè àti forúkọ sílẹ̀ ní ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba NYS nígbàkúùgbà yípo ọdún, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn àṣàyàn lè dínkù ní ìta àkókò ìforúkọsílẹ̀ ìbílẹ̀.
- Àwọn ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba lè má béèrè nípa ipò ìṣíwá àti pé wọn kò ní pín àlàyé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ fún ètò ilé-ẹ̀kọ́ ojoojúmọ́ kankan. Àwọn ètò ìgbà èwe ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ pẹ̀lú wákàtí gígùn lè ní àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́ tó dá lórí owó-àpawọlé tàbí ìṣíwá.
- Àlàyé Àwọn ilé-ìwé Ìjọba Ìlú New York
  - Fún àlàyé lórí bí a ṣe lè béèrè fún ìtumọ̀ àti àwọn iṣẹ́ ìtumọ̀ ní Ilé-ìwé Ìjọba NYC, ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/hello tàbí pe 718-935-2013.
  - Fún àlàyé lórí ìlànà àwọn gbígbàwọlé ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/enrollment/enrollment-help/new-students.
  - Láti wá àti béèrè wáyé sí Ilé-ìwé Ìjọba NYC, ṣàbẹ̀wò sí myschools.nyc, pe 311, tàbí ṣàbẹ̀wò sí Ibùdó Ìrànlọ́wọ́ Ìdílé kan. Àwọn agbègbè Ibùdó Ìrànlọ́wọ́ Ìdílé ni a lè rí ní schools.nyc.gov/fwc
  - Àkókò ìforúkọsílẹ̀ yàtọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú oríṣiríṣi àwọn ìpele akẹ́kọ̀ọ́. Láti rí Àkókò Ìgbàwọlé Fall 2024, ṣàbẹ̀wò sí schools.nyc.gov/enroll.

**Ìfòfinde lílo tẹlifóònù alágbèéká ní àwọn Ilé-ìwé ìjọba.**

- Ìpínlẹ̀ New York gbé òfin tuntun kan jáde ní oṣù karùn-ún ọdún 2025 tí ó dín lílo fóònù alágbèéká àti àwọn ẹ̀rọ tí ó lè wọ ẹ̀rọ-ayélujára kù fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní àkókò tí wọ́n wà ní ilé-ìwé.
- Wọ́n lè gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láyè láti lo àwọn ẹ̀rọ (fónù) wọn, tó bá jẹ́ pé wọ́n nílò rẹ̀ fún ṣíṣe ìtumọ̀, ògbufọ̀, ìṣòro ìlera, tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ pàjáwìrì nínú ìdílé.
- Àwọn òbí yóò ṣì ní àǹfààní láti bá àwọn ọmọ wọn sọ̀rọ̀ nípasẹ̀ àwọn òṣìṣẹ́ ilé-ìwé lójú ọjọ́.
- Átúnṣe òfin náà yóò máa wáyé látọ̀dọ̀ àgbègbè ilé-ìwé kọ̀ọ̀kan tí ó dá lórí àwọn àìní àgbègbè àti èsì láti ọ̀dọ̀ àwọn ìdílé.
  - Ilé-ìwé ìjọba tí ó wà ní NYC yóò pa láṣẹ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pé kí wọ́n kó fóònù wọn pamọ́ nígbà tí wọ́n bá wà ní ilé-ìwé.

**Ìrànlọ́wọ́ Owó Kọ́lẹ́ẹ̀jì**

- Gba Ìrànlọ́wọ́ ní UnderstandingFAFSA.org, wẹ́búsáìtì kan tí ó ń pèsè àwọn ìtọ́nisọ́nà àti àwọn ohun èlò fún àwọn ọmọ ilé-ìwé àti àwọn ìdílé tí ń wá owó fún kọ́lẹ́ẹ̀jì.
  - Ìtọ́nisọ́nà Bí-A-Ṣe lè ṣeé FAFSA ọ̀fẹ́ wọn fún Àwọn ọmọ ilé-ìwé gíga wà ní oríṣi èdè mẹ́wà
  - Wẹ́búsáìtì náà ti ṣe ìmúdójúìwọn àwọn ojúewé bí-a-ṣe lè ṣeé fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí kò ní ìwé-àṣẹ àti àwọn ìdílé aṣíkiri
- Àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ owó Ìpínlẹ̀ New York
  - Ètò Ìrànlọ́wọ́ Owó Ìkẹ́kọ̀ọ́ (TAP) ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn olùgbé New York tí ó yẹ láti san owó ìkẹ́kọ̀ọ́ ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tí a fọwọ́sí ní NYS.
    - Àmì-èyẹ TAP ọdọọdún lè tó $5,665. Nítorí TAP jẹ́ ẹ̀bùn, a kò nílò láti san án padà.
    - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/tap
  - Ẹ̀kọ́-ọ̀fẹ́ Excelsior
    - Ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ Excelsior, pẹ̀lú àpapọ̀ àwọn ètò ìrànlọ́wọ́ owó àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn, ń jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ sí kọ́lẹ́ẹ̀jì SUNY tàbí CUNY níbi tí wọn kì í sanwó ìkẹ́kọ̀ọ́.
    - Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti àwọn ìdílé tí owó-àpawọlé ọ́dọọdún wọn jẹ́ $125,000 tàbí kéré sí i ní ó ní ẹ̀tọ́ láti béèrè.
    - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/excelsior
  - Aṣòfin José Peralta New York State DREAM Act fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn ní àǹfàní sí àwọn ẹ̀bùn àti ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ tí NYS ń ṣàkóso tí ó ń ṣe àtìlẹ́yìn fún iye owó ẹ̀kọ́ gíga wọn.
    - Fún àlàyé síwájú síi tàbí láti béèrè fún, ṣàbẹ̀wò sí hesc.ny.gov/dream

# Ìrólágbára owó



**Àfikún Ètò Ìrànwọ́ fún Àwọn Tí Kò Níṣẹ́ Lọ́wọ́**

- Ní ọdún yìí, Ìpínlẹ̀ New York ń ṣe àfikún sí owó ìrànwọ́ fún àwọn ẹni tí wọn kò níṣẹ́ lọ́wọ́ àti ìdínkù sí owó orí fún àwọn ìṣòwò.
- Láti bẹ̀rẹ̀ ní 6 Oṣù Kẹwàá, Ọdún 2025, iye tó pọ̀ jù lọ tí wọ́n lè san lọ́sọ̀ọ̀sẹ̀ fún àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n pàdánù iṣẹ́ wọn láìjẹ́ pé àwọn fúnra wọn ló fà á, tí wọ́n sì múra tán, tọkàntọkàn, tí wọ́n sì lè ṣiṣẹ́ yóò máa lọ sókè láti $504 tó wà nísinsìnyí sí $869.
    - Owó ìrànwọ́ tó pọ̀ jù lọ ni iye tó ga jùlọ tó wà fún àwọn aráàlú New York tí wọn kò níṣẹ́ lọ́wọ́ tí ó sì dá lórí owó tó ti wọlé fún wọn tẹ́lẹ̀.
    - Bí o kò bá tiẹ̀ rí iye tó pọ̀ jùlọ gbà, o ṣì lè rí àfikún sí iye owó ìrànwọ́ rẹ tí ó ń wọlé fún ọ.
    - A ó ṣe àtúnṣírò iye owó tuntun náà ní tààràtà ní ìbámu pẹ̀lú owó tí o ti rí gbà tẹ́lẹ̀
    - Àlékún sí iye owó ìrànwọ́ yìí máa bẹ̀rẹ̀ ní ọ̀sẹ̀ Oṣù Kẹwàá ọjọ́ 13. O ò sì nílò láti ṣe ohunkóhun kí o tó lè rí àfikún sí owó yìí gbà.
- Láti mọ iye owó ìrànwọ́ aláìníṣẹ́ lọ́wọ́ tí ó yẹ kí o máa gbà lọ́sọ̀ọ̀sẹ̀, ṣàbẹ̀wò sí ux.labor.ny.gov/benefit-rate-calculator
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/unemployment-insurance-ui-trust-fund-faq
- Láti béèrè fún owó ìrànwọ́ fún ẹni tí kò níṣẹ́ lọ́wọ́, ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/unemployment

**Owó Ìrànwọ́ Ọ̀wọ́n Gógó Ọjà**

- Àwọn aráàlú New York máa gba owó ìrànwọ́ ọ̀wọ́n gógó ọjà fún ìgbà àkọ́kọ́.
- Owó tí wọ́n máa ń san lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo yìí wà fún àwọn aráàlú New York tí wọ́n ti san owó orí tó pọ̀ sí i nítorí owó ọjà tó ti wọ́n gógó
- Láti kúnjú ìwọ̀n fún owó ìrànwọ́ ọ̀wọ́n gógó ọjà, o gbọ́dọ̀:
    - Ti fi Fọ́ọ̀mù IT-201 sílẹ̀, Ìwé Ìfilọ́lẹ̀ Owó Orí ti Olùgbé Ìpínlẹ̀ New York fún ọdún 2023.
    - Ìròyìn owó tó ń wọlé fún ọ wà ní àwọn sàkání tó kúnjú ìwọ̀n.
        - Láti mọ̀ tí o bá wà ní sàkání tó kúnjú ìwọ̀n, ṣàbẹ̀wò sí tax.ny.gov/pit/inflation-refund-checks.htm
    - O gbọ́dọ̀ wà ní abẹ́ àbójútó ẹlòmíràn tó ń sanwó orí.
- Tí o bá kúnjú ìwọ̀n, a ó fi àwọn sọ̀wédowó ránṣẹ́ sí ọ àti pé o kò nílò láti ṣe ohunkóhun.
    - Fífi àwọn sọ̀wédowó ránṣẹ́ yóò bẹ̀rẹ̀ ní ìparí Oṣù Kẹsán Ọdún 2025 àti pé ìfiránṣẹ́ yó sì tẹ̀síwájú fún bíi ọ̀sẹ̀ mélòó kan.
    - A ó fi sọ̀wédowó ránṣẹ́ sí àdírẹ́ẹ̀sì tó wà nínú ìwé owó orí rẹ ti àìpẹ́ yìí.
    - Kò sí àyè ìsanwó tààrà.
- Kíyèsi fún àwọn oní jìbìtì
    - Ẹ̀ka tó ń rí sí Owó Orí àti Ìṣúná-owó kìí kàn sí àwọn tó ń sanwó orí nípa owó ìrànwọ́ ọ̀wọ́n gógó ọjà.
    - O kò nílò láti pèsè àfikún ìsọfúnni tí o bá fẹ́ gba sọ̀wédowó.
    - Tí ẹnikẹ́ni tó sọ pé òún jẹ́ òṣìṣẹ́ Ẹ̀ka Owó Orí bá kàn sí ọ nípa owó ìrànwọ́ ọ̀wọ́n gógó ọjà, ṣe ìfisùn rẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
- Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí tax.ny.gov/pit/inflation-refund-checks.htm

**Àwọn ìsọfúnni ẹni tó ń sanwó orí fún àwọn Olùfiránṣẹ́ pẹ̀lú lílo ITIN**

- Ní Oṣù Kẹrin Ọdún 2025, Ẹ̀ka Tó Ń Rí sí Owó Tó Ń Wọlé Sápò Ìjọba (IRS) fohùn ṣọ̀kan pẹ̀lú Ẹ̀ka Ààbò Ìlú láti máa pín àwọn àkọsílẹ̀ ìgbẹ́gẹ́ lórí àwọn tí wọn kò ní ìwé ìgbélú tí àṣẹ lílé wọn kúrò nílùú ti jáde tí wọ́n ṣì ń sanwó orí.
- Fún àlàyé síwájú síi nípa ti ITIN àti ìpamọ́ ẹ̀gbà, ṣàbẹ̀wò sí nyic.org/resources-training/taxpayer-information-for-itin-filers

# Ìjọba tiwa-n-tiwa

**Ìdìbò gbogbogbòò Ìjọba-àapapọ̀, Ìjọba-ìpínlẹ̀, àti Ìjọba-ìbílẹ̀**

- Ọjọ́ ìdìbò gbogbogbòò fún ìjọba àpapọ̀, ìjọba ìpínlẹ̀ àti ìjọba ìbílẹ̀ jẹ́ 4 Oṣù kọkànlá, 2025.
- Ọjọ́ ìkẹhìn láti forúkọ sílẹ̀ fún ìdìbò gbogbogbòò yìí, tàbí láti yí àdírẹ́sì rẹ padà, jẹ́ 25 Oṣù kẹwà, 2025.
- Láti ṣe àtúngbéyẹ́wò ìforúkọsílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi olùdìbò àti ìdarapọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ òṣèlú, ṣàbẹ̀wò sí voterlookup.elections.ny.gov
    - Tí ọ bá ní ìbéèrè nípa ipò ìforúkọsílẹ̀ rẹ, kànsí Ìgbìmọ̀ Ìdìbò orílẹ̀-èdè rẹ www.elections.ny.gov/CountyBoards.html
    - Àwọn olùgbé NYC: ṣàbẹ̀wò sí vote.nyc
- Àkókò ìdìbò ìṣáájú fún ìdìbò gbogbogbòò yóò wà láti 25 Oṣù kẹwà títí dé 2 Oṣù kọkànlá.
- Ọ̀jọ́ ìkẹhìn láti béèrè fún ìwé ìdìbò ìfiránṣẹ́ ni 25 Oṣù kẹwà. Ìwé ìdìbò náà gbọ́dọ̀ ní àmì-ìfiwéránṣẹ́ ti 4 Oṣù kọkànlá tàbí ṣáájú ìgbà náà, àti pé ilé-iṣẹ́ ìgbìmọ̀ ìdìbò gbọ́dọ̀ ti gbà á ní 11 Oṣù kọkànlá.
    - Láti bèèrè fún ìwé ìdìbò ìfiránṣẹ́, ṣàbẹ̀wò sí elections.ny.gov/request-ballot
- Fún ìdìbò 2025, àwọn èèyàn New York máa dìbò fún àwọn alákòóso ìlú, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ ìgbìmọ̀ ìlú, àti àwọn ipò ìjọba àti ilé-ẹjọ́ mìíràn.
- Àwọn olùdìbò ní ìlú New York City yóò tún ní àwọn àbá ìdìbò mìíràn lórí ọ̀rọ̀ ilé àti ìdìbò ìjọba ìbílẹ̀. Láti mọ̀ síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí nycvotes.org




**Forúkọsílẹ̀ láti dibò**

- O lè forúkọ sílẹ̀ láti dìbò tí o bá jẹ́ ọmọ ọdún 16+, ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà àti olùgbé NY fún ó kéré tán ọjọ́ 30 ṣáájú ìdìbò náà.
    - Tí o bá jẹ́ ọmọ ọdún 16 tàbí 17, o lè forúkọ sílẹ̀ tẹ́lẹ̀ láti dìbò ṣùgbọ́n o kò lè dìbò títí di ọmọ ọdún 18.
    - Ìwọ kò lè forúkọ sílẹ̀ láti dìbò tí o bá wà lẹ́wọ̀n fún ìdájọ́ ìwà ọ̀daràn tàbí kí ilé ẹjọ́ dá ọ lẹ́jọ́ pé ọpọlọ rẹ kò ní agbára.
- Ìgbìmọ̀ Ìdìbò NYS: elections.ny.gov/VotingRegister
- Ìgbìmọ̀ Ìdìbò NYC: vote.nyc/page/register-vote
- Forúkọsílẹ̀ lórí ayélujára (tí o bá ní Ìwé-àṣẹ Awakọ̀ NYS, Ìyọ̀nda tàbí Ìdánimọ̀ Ti kii ṣe ti Awakọ̀): voterreg.dmv.ny.gov/MotorVoter
- Béèrè ìwé fọ́ọ̀mù ìforúkọsílẹ̀ kan nípasẹ̀ fóònù (wà ní Gẹ̀ẹ́sì tàbí Spanish): 1-800-FOR-VOTE (1-800-367-8683)
- Kò dá ọ lójú bóyá o forúkọ sílẹ̀ láti dìbò? Ṣàyẹ̀wò ipò ìforúkọsílẹ̀ olùdìbò rẹ ní voterlookup.elections.ny.gov

**Àwọn ẹ̀tọ́ rẹ ní ibùdó ìdìbò**

- Àwọn olùdìbò lè ṣàbẹ̀wò sí ÈYÍKÉYÌÍ nínú àwọn Ibùdó Ìdìbò Ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ní agbègbè tí wọ́n ń gbé, àyàfi ní Ìlú New York, níbi tí wọ́n tí ń yàn àwọn olùdìbò nípasẹ̀ àdírẹ́sì sí ibi ìdìbò ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ KAN.
- Tí o bá gbàgbọ́ pé o ní ẹ̀tọ́ olùdìbò tí o sì ti forúko sílẹ̀ ní àsìkò láti dìbò, ṣùgbọ́n a kò lè rí orúkọ rẹ lórí ìwé ìdìbò, o lè béèrè fún ìwé ìdìbò ìgbà ránpẹ́ tàbí ìbúra ẹ̀rí.
- Ìwọ kò nílò láti ṣe àgbékalẹ̀ ìdánimọ̀ níbi ìdìbò kódà bí o bá jẹ́ olùdìbò fún ìgbà àkọ́kọ́.
- Ìwọ sì lè dìbò tí o bá ń ní ìrírí àìnílé.
- Ní àwọn ipò kan, o sì lè ní ẹ̀tọ́ láti dìbò tí wọ́n bá ti dá ọ lẹ́bi ìwà ọ̀daràn.
- Fún àwọn ìbéèrè ẹ̀tọ́ síi: www.nycvotes.org/how-to-vote/voting-rights
- Àwọn òṣìṣẹ́ kan ní ìpínlẹ̀ New York ní ẹ̀tọ́ láti gba ìsinmi wákàtí méjì tí wọ́n sanwó fún láti lè dìbò. Ṣàyẹ̀wò láti rí bóyá o pegedé: www.elections.ny.gov/NYSBOE/elections/TimeOffToVoteFAQ.pdf

**Láti mọ díẹ̀ sí nípa àwọn ètò ìdìbò àti bí wọn ṣe ń ṣiṣẹ́, wo àwọn fọ́nrán wa: nyic.me/civics**

# Mọ Àwọn ẹ̀tọ́ Rẹ



**Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àwọn alájọṣepọ̀ gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa ẹ̀tọ́ wọn nígbàkúùgbà tí wọ́n bá ń ṣe pẹ̀lú Agbófinró Ìwọlé-jáde àti Ẹ̀só-aṣọ́bodè (ICE), Ìpàáro Àálà, tàbí àwọn agbófinró mìíràn.**

**Tí agbófinró ìwọlé-jáde tàbí àwọn agbófinró mìíràn bá dá ọ dúró, rántí:**

- Fara balẹ̀. Má sáré. Má ṣe dènà tàbí dí òṣìṣẹ́ náà lọ́wọ́.
- Má ṣe parọ́ tàbí pèsè àwọn ìwé èké.
- O ní ẹ̀tọ́ lati dakẹ. Ohunkóhun tí o bá sọ ni a lè lò láti fi takò ọ́
- Tí aṣojú kan bá béèrè bóyá wọ́n lè wá ọ tàbí àwọn ohun ìní rẹ, o ní ẹ̀tọ́ láti sọ pé rárá.
    - Síbẹ̀síbẹ̀, o lè má kọjú ìjà gbangba síi.
    - Àwọn ọlọ́pàá lè tẹ́ aṣọ rẹ mọ́lẹ̀ tí wọ́n bá fura sí ohun ìjà.
- Tí o kò bá jẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí aṣojú agbófinró ìwọlé-jáde sì béèrè fún ìwé ìwọlé rẹ, o gbọ́dọ̀ fi hàn wọ́n tí o bá ní wọn pẹ̀lú rẹ.
- Tí wọ́n bá dá ọ dúró, tí wọ́n tì ọ́ mọ́lé, tàbí kí àwọn agbófinró ṣe inúnibíni sí ọ, gbìyànjú láti gba orúkọ aṣojú náà, nọ́mbà, àti àlàyé ìdánimọ̀ mìíràn.
- Ìwọ tàbí ẹlòmíràn ní agbègbè náà lè ya fídíò tàbí ìgbàsílẹ̀ ohùn ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró. O tún lè kọ ohun tó ṣẹlẹ̀ sílẹ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá kúrò.
- Kò bófin mu fún àwọn agbófinró láti ṣe ìdádúró èyíkéyìí, ìwádìí, ìtìmọ́lé, tàbí ìkọlù tí ó dá lórí ẹ̀yà rẹ, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ẹ̀sìn, ìbálòpọ̀, tàbí ẹ̀yà.

**O lè ṣe ìjábọ̀ ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn aṣojú ìjọba àpapọ̀ sí Immigrant Defense Project (IDP).**

**IDP tún pèsè àlàyé òfin àti ìtọ́kasí fún àwọn aṣíkiri tí wọ́n ti mú, tí wọ́n ti gba tíkẹ́ẹ̀tì, tàbí tí wọ́n dá lẹ́bi ìwà ọ̀daràn. Pe 212-725-6422 tàbí ímeèlì info@immdefense.org**

**Àwọn ààyè Ìdákọ́ńkọ́**

- Ilé rẹ àti àwọn "ààyè ìdákọ́ńkọ́" mìíràn (gẹ́gẹ́ bí àwọn agbègbè òṣìṣẹ́ nìkan ní ibi iṣẹ́) gbé ààbò pàtàkì tí àwọn ààyè gbogbogbò kò ní. Àwọn ọlọ́pàá kàn lè wọ ààyè ìdákọ́ńkọ́ tí wọ́n bá ní ìfọwọ́sowọ́pọ̀ rẹ tàbí kí wọ́n fi ìwé àṣẹ ìdájọ́ hàn ọ́ (tí adájọ́ buwọ́lù).

**Àwọn àgbègbè Ààbò**

- Ní Oṣù Kinní Ọdún 2025, ìjọba Trump fagilé àlàkalẹ̀ ọlọ́jọ́ pípẹ́ tó ń darí ICE àti CBP láti yàgò fún gbígbófinró ìṣíwọ̀lú ní "àwọn ààyè tí òfin ní ìkálọ́wọ́kò sí" tàbí "agbègbè tó wà lábẹ́ ìdáàbòbò" bíi àwọn ilé-ẹ̀kọ́, iléeṣẹ́ ìtọ́jú ìlera, àti àwọn ààyè ìjọsìn.
- Síbẹ̀síbẹ̀ pẹ̀lú ìyípadà yìí, àwọn aráàlú New York ṣì tún ní ìdáàbòbò díẹ̀ ní àwọn ààyè yìí.
- Àwọn Àṣẹ Ìgbìmọ̀ Ìjọba Ìpínlẹ̀ New York 2018 kan fòfin de àwọn agbófinró ìṣíwọ̀lú ní àwọn iléeṣẹ́ ìpínlẹ̀ New York bíi ilé-ẹ̀kọ́ tàbí ilé-ìwòsàn àyàfi tí ICE bá ní ìwé-àṣẹ láti ọwọ́ ilé-ẹjọ́.
- Àgbékalẹ̀ Òfin Ìdáàbòbò Ilé-ẹjọ́ Wa dáàbòbo àwọn aráàlú New York lọ́wọ́ fífi òfin mú ẹni ní ilé-ẹjọ́ ìpínlẹ̀, ìlú àti ti agbègbè láìsí ìwé-àṣẹ láti ilé-ẹjọ́.
- ICE àti àwọn aṣojú òfin mìíràn ò leè wọlé sí "àwọn ààyè aládàáni" láì ní ìwé-àṣẹ láti ilé-ẹjọ́ tàbí ìyọnda oníwun.

**Mọ̀ nípa ìwà ìbàjẹ́ àwọn aṣíkiri.**

- Òfin àwọn aṣíkiri le. Ṣọ́ra nígbàtí o bá ń jíròrò ipò rẹ pẹ̀lú èyíkéyì ènìyàn tàbí ìṣòwò
- Agbẹjọ́rò tàbí Aṣojú Ẹká ti Ìdájọ́ (DOJ) tí a fọwọ́sí fún ìmọ̀ràn òfin nìkan ní ó yẹ kí o bá sọ̀rọ̀ lórí ipò rẹ.
- Má ṣe gba ìrànlọ́wọ́ àwọn aṣíkiri láti ọ̀dọ̀ "notario," aṣojú ìrìn-àjò, ìgbáradì owó orí, ìgbáradì fọ́ọ̀mù, tàbí ẹlẹ́rì-òfin. Ní orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà, "notario" kì í ṣe agbẹjọ́rò!

**Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ẹjọ́ rẹ tàbí tí o ní àwọn ìbéèrè ìwọlé gbogbogbò, pe Ọ́fíìsì fún Ará Amẹ́ríkà tuntun (ONA) Ojú-òpó-ìyára ní 1-800-566-7636.**

# Ààbò Àgbègbè



**Gbogbo ènìyàn, láìka ipò ìwọlé tàbí ìdánimọ̀ sí, yẹ kí ó wà ní ààbò ní agbègbè wọn.**

### Ẹ̀ṣẹ̀ Ìkóríra àti Ẹ̀tanú

- Ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ tí ó jẹ́ ìwúrí nípasẹ̀ ẹ̀tanú sí ẹ̀yà ènìyàn, àwọ̀, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ìdílé, ọkùnrin àti obìnrin, ẹ̀sìn, ìṣe ẹ̀sìn, ọjọ́ orí, àìlera tàbí ìbálòpọ̀.
- Ìpínlẹ̀ New York ní Agbófinró Ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra láti yanjú ìlọsíwájú nínú àwọn ìròyìn nípa ìdẹ́rùbà, ìnira àti ìwà ipá.
- Tí o bá rí ohun kan tàbí jẹ́ olùfaragbá ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra:
  - Sọ ọ́ fún Ìpín NYS ti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn. Pe 1-888-392-3644, tẹ " HATE " sí 81336, tàbí lọ sí forms.ny.gov/s3/Hate-Crime-Tips. O lè ṣàbẹ̀wò sí dhr.ny.gov fún àlàyé síwájú síi
  - Láti ṣe ìjábọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra tí ó ń lọ lọ́wọ́ tàbí pàjáwìrì èyíkéyì, pe 911 lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
- Nígbà tí wọ́n bá ròyìn ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra, gbogbo àlàyé nípa ìrírí rẹ, ìdánimọ̀ rẹ, àti àwọn mìíràn ṣì wà ní ìkọ̀kọ̀.
- O lè ṣe ìjábọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ ìkóríra kí o sì gba àwọn iṣẹ́ láìka ipò ìwọlé rẹ sí.

### Àwọn Ohun Àmúlò Agbègbè

- Ọ́fíìsì Ìlú New York fún Ìdènà Ẹ̀ṣẹ̀ Ìkóríra ń pèsè àwọn iṣẹ́, àwọn ohun èlò, àti àtìlẹ́yìn fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ agbègbè àti àjọ. Àwọn ohun èlò wà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè. Fún àlàyé síwájú síi, ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/stophate.
- Ilé-iṣẹ́ fún Ẹ̀kọ́ Gbígbógun ti Ìwà Ipá ń ṣiṣẹ́ láti dènà, ṣe ìdíwọ́, àti láti wò ó sàn kúrò nínú ìwà ipá ìkóríra ní àwọn agbègbè New York. Wọ́n ní àwọn ètò ẹ̀kọ́ lórí ìdáàbòbò ara wọn, àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó wà nítòsí, àti agbára àwọn ọ̀dọ́. Pe 1-718-788-1775 tàbí ṣàbẹ̀wò sí caeny.org fún àlàyé síwájú síi.

### Sísopọ̀ pẹ̀lú Àgbègbè

- AAPI
  - Asian Americans for Equality: 212-979-8381, aafe.org
  - Chhaya for South-Asian and Indo-Caribbean communities: 718-478-3848, chhayacdc.org
  - Korean Family Service Center: 718-460-3800, kafsc.org
  - MinKwon Center for Community Action: 718-460-5600, minkwon.org
  - National Federation of Filipino American Associations New York: 212-684-0542, naffaa.org
  - Sikh Coalition: 516-930-0302, sikhcoalition.org
- Ará Áfíríkà
  - African Communities Together: 347-746-2281, africans.us
  - African Services Committee: 212-222-3882, africanservices.org
  - Sauti Yetu Center For African Women: 718-665-2486, sautiyetu.us
- Mùsùlùmí/Lárúbáwá
  - Arab American Association of New York: 718-745-3523, arabamericanny.org
  - Council on American-Islamic Relations of New York: 646-665-7599, cair-ny.org
  - Muslim Community Network: 347-519-2755, mcnny.org
- Àìpéra
  - Center for Disability Rights: 585-546-7510, cdrnys.org
  - Disability Rights New York: 518-432-7861, drny.org
- Hispanic/Latino
  - Hispanic Federation: 866-432-9832, hispanicfederation.org
  - Latino Commission on AIDS: 212-584-9325, latinoaids.org
  - Mixteca: 718-965-4795, mixteca.org
  - TransLatinx: 646-882-2000, translatinxnetwork.org
- LGBTQ+
  - Caribbean Equality Project: 347-709-3179, caribbeanequalityproject.org
  - Gay, Lesbian, Bisexual and Transgender Community Center: 212-620-7310, gaycenter.org
  - New York City Gay and Lesbian Anti-Violence Project: 212-714-1141, avp.org
- Abínibí Amẹ́ríkà àti Abínibí Alaska
  - American Indian Community House: 646-575-3638, aich.org
  - North American Indigenous Center of New York: 516-930-0302, naicny.org

# Àwọn ohun àmúlò iṣẹ́ NYS



### Ọ́fíìsì NYS fún Lílò Èdè

- Ọ́fíìsì NYS fún Lílò Èdè ń ṣàkóso àwọn iṣẹ́ lílò èdè fún mílíọ̀nù àwọn aráàlú New York tí wọn ò fi bẹ́ẹ̀ mọ èdè Gẹ̀ẹ́sì sọ dáadáa.
- Láti mọ àwọn ẹ̀tọ́ rẹ sí ògbufọ̀ àti àwọn iṣẹ́ ìtúmọ̀ èdè, ṣàbẹ̀wò sí ogs.ny.gov/know-your-rights
- Láti ṣe ìfisùn nípa lílò èdè, ṣàbẹ̀wò sí languageaccess.ny.gov/en-US**.**
- Láti gba àwọn ohun èlò tí a fi ń rí èdè lò tàbí láti béèrè àwọn ohun èlò tí a fi ń túmọ̀ èdè, fi ìbéèrè náà ránṣẹ́ sí àwọn àjọ alátìlẹyìn survey.alchemer.com/s3/8252338/OLA-Questionnaire

### Ọ́fíìsì NYS fún Ará Amẹ́ríkà tuntun

- Tí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ bá nílò ìrànlọ́wọ́ òfin ọ̀fẹ́, pe ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀-ìyára náà ní 1-800-566-7636. Gbogbo àlàyé ìpè jẹ́ àṣírí. Ìrànlọ́wọ́ wà ní èdè 200+.

### Ẹ̀ka Ètò Ìlera NYS

- Béèrè fún Ìtọ́jú Ìlera: pe 1-855-355-5777 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nystateofhealth.ny.gov.

### Ọ́fíìsì NYS fún Ìlera Ọpọlọ

- Fún àwọn ìbéèrè nípa àwọn iṣẹ́ ìlera ọpọlọ tàbí láti wá olùpèsè iṣẹ́ ìlera ọpọlọ, pe 1-800-597-8481 tàbí ṣàbẹ̀wò sí omh.ny.gov.
- Ìlà-ìpè ìyára Ìdènà Ìṣekúparaẹni Ìjọba àpapọ̀ : Tí ẹ̀mí rẹ tàbí ti ẹlòmíràn bá wà nínú ewu tó ń súnmọ́, pe 911. Tí o bá wà nínú wàhálà àti nílò ìrànlọ́wọ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, pe 1-800-273-8255 tàbí Tẹ "GOT5" sí 741-741.

### Ọ́fíìsì NYS fún Ìdènà ti Ìwà-ipá Ilé

- Tí ìwọ tàbí ẹlòmíràn bá wà nínú ìbáṣepọ̀ tí ẹlòmíràn ń ṣàkóso nípasẹ̀ ọ̀rọ̀, ti ara, tàbí ìlòkulò ìbálòpọ̀, tàbí àwọn ọgbọ́n míràn, pe Ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀ NYS fún Ìwà Ipá Inú Ilé ní 1-800-942-6906.
- Láti bá agbẹjọ́rò sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀rọ ayélujára, ṣàbẹ̀wò sí opdv.ny.gov. Ó wà ní 24/7 ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè.

### Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti NYS

- Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti ṣe ìpinnu láti dáàbò bo àti ìgbéga ààbò àti ìlera àwọn òṣìṣẹ́, owó oṣù, àti ipò iṣẹ́.
- Fún àlàyé nípa owó oṣù àti òfin wákàtí, ìlera ibi iṣẹ́ àti ààbò, tàbí láti fi ẹ̀sùn kan, pe 1-888-469-7365 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/safety-and-health
- Fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú Ìdánilójú Àìríṣẹ́ṣe, pe 1-888-209-8124 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dol.ny.gov/ unemployment/unemployment-insurance-assistance.

### Ìpín NYS ti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn

- Òfin Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn ní New York fòfin de ìyàtọ̀ ní àwọn agbègbè bíi ìgbanisíṣẹ́, ilé, gbèsè, ẹ̀kọ́, àti àwọn ibi ìgbé gbogbogbò, tí ó dá lórí ọjọ́ orí, ẹ̀yà, ìpilẹ̀ṣẹ̀ orílẹ̀-èdè, ìbálòpọ̀, ìbálòpọ̀, ìdánimọ̀ ọkùnrin àti obìnrin tàbí ìfihàn, ipò ìgbéyàwó, àìlera, ipò ológun, àti àwọn ẹ̀ka mìíràn.
- Tí o bá rò pé wọ́n ti yà ọ́ sọ́tọ̀, fi ẹ̀sùn sílẹ̀ ní 1-888-392-3644 tàbí ṣàbẹ̀wò sí dhr.ny.gov.

### Ètò-Ilé NYS

- Fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú wíwá ilé tí kò wọ́n, pe 1-877-428-8844 tàbí ṣàbẹ̀wò sí nyhousingsearch.gov.
- Fún àlàyé lórí tẹ́tẹ́ ilé tí kò wọ́n ní ìlú New York, pe 212-863-7990 tàbí ṣàbẹ̀wò sí housingconnect.nyc.gov.
- Fún àlàyé lórí ẹ̀tọ́ àwọn ayálégbé ní Ìpínlẹ̀ New York, ṣàbẹ̀wò sí ag.ny.gov/publications/residential-tenants-rights-guide.

### Ọ́fíìsì NYS fún Àwọn iṣẹ́ Olùfaragbá

- Tí ìwọ tàbí ẹnìkan tí o mọ̀ bá ti ní ìrírí ìwà ìkórìra, Ọ́fíìsì NYS fún Àwọn iṣẹ́ Olùfaragbá lè ní àǹfàní láti ṣe ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú owó ìtọ́jú ìṣègùn àti ìnáwó ìmọ̀ràn, ìsìnkú àti iye owó ìsìnkú, owó oṣù tí ó sọnù, àti àwọn irúfẹ́ ìrànlọ́wọ́ mìíràn.
- Pe 1-800-247-8035 tàbí ṣàbẹ̀wò sí ovs.ny.gov fún àlàyé síwájú síi.

Láti wo ìwé yìí lórí ẹ̀rọ ayélujára tàbí ní àwọn èdè míràn, ṣàbẹ̀wò sí nyic.org/KYR tàbí ya àwòrán kóòdù yìí:

Tí o bá ní àwọn ìbéèrè tàbí àwọn àsọyé nípa irinṣẹ́ yìí tàbí àlàyé nínú rẹ, jọ̀wọ́ kan si:
Bryan Lee – blee@nyic.org

Àgbáríjọ Àjọ Ìwọlé-jáde New York (NYIC) jẹ́ ìlànà àpapọ̀ àti àjọ alátìlẹ́yìn tí ó ń ṣojú fún àwọn ẹgbẹ́ aṣíkiri àti àwọn ẹgbẹ́ ẹ̀tọ́ àwọn aṣíkiri àti àwọn asásálà tó lé ní 200 káàkiri New York.

A fojú inú wo ìpínlẹ̀ New York tí ó lágbára nítorí pé gbogbo ènìyàn ni wọ́n gbà, tí wọ́n ń tọ́jú wọn dáadáa, tí wọ́n sì fún wọn ní àǹfàní láti lépa àlá wọn. Iṣẹ́ wa ni láti so àwọn aṣíkiri, àwọn ọmọ ẹgbẹ́, àti àwọn alájọṣepọ̀ pọ̀ kí gbogbo àwọn ará New York lè gbilẹ̀.

**New York Immigration Coalition**
131 W 33rd St, Ste 610
New York, NY 10001
212 627 2227
nyic.org